# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,591 TUESDAY DECEMBER 21, 1965 (2D)


## Ọdaran Kan Ji Eran Gbe!

IBADAN:— Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni Adajọ ile ẹjọ kekere ti ilu Ibadan paṣẹ pe ki Ọlọṣa Ọkunrin kan Joseph Bamidele yara lọ fi ẹwọn ọdun mẹta jura lori ẹsun pe ọdaran na Bamidele ẹni ọdun mẹdọgbọn ji ẹran ti nwọn ti pa gbe eyiti o jẹ wipe ẹwọn ọdun mẹta pẹlu iṣẹ alaṣekara ni Adajọ ile ẹjọ na ni ki o yara lọ.

Ninu ọrọ Ọlọp to ba Ọdaran na ṣe ẹjọ ni o ti ṣe alaye pe ọdaran na Joseph Bamidele lọ wọ inu ṣọbu ti Obinrin kan ti nwọn npe ni Christiana Adebiyi ni ọjọ kọkandinlogun oṣu to kọja lọ yi ti o si ji ẹran kan ti o wa ninu awo onjẹ kan to wa ninu ṣọbu na.

Ninu ọrọ Ọdaran Ọlọṣa na ni o ti ṣe alaye fun ile ẹjọ pe on ko ji ẹ r a n kankan ati pe oṣe ni nwọn pa irọ mọ on.

Ninu idajọ Adajọ Agba ile ẹjọ kekere na Ọgbẹni A. O. Lapitẹ ti ṣe alaye pe on gba gbogbo ọrọ ti Ọlọpa to ba ọdaran na ṣe ẹjọ ro niwaju ile ẹjọ ati pe ko si irọ kankan ninu ọrọ Ọlọpa na nitoripe Ọdara Ọkunrin na ti kuna lati fun Ọlọpa ni idahun gbogbo ẹsun ti Ọlọpa na ka si i lẹsẹ.

Adajọ agba ile ẹjọ na si paṣẹ pe ki Ọdaran na yara lọ fi ẹwọn ọdun mẹta pẹlu iṣẹ aṣekara lọ jura.

# ẸGBẸ AFẸNIFẸRE KILỌ FUN ALHAJI BALEWA LORI ỌRỌ ILE RHODESIA

IBADAN:- Ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o wa ni ilu Ibadan ti kesi Alhaji Tafawa Balewa lori ọ r ọ ilẹ Rhodesia pe, ọrọ na ko kan lọwọ ati ii ẹsẹ paapa ẹtọ Alhaji Balewa ni pe, ki o kọkọ yọ igi ti o wa ninu oju rẹ na ki o to yọ ẹrun igi ti o wa loju Ọgbẹni Ian Smith alakoso ilẹ Rhodesia.

Ninu ọrọ ti Ọgbẹni Bọla Ige, akọwe ifi eto ẹgbẹ sode fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o ti sọ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi pe, ile ni o yẹ ki Alhaji Balewa ti kọ ẹsọ lọ sode, o ni gbogbo ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun yẹyẹ ni Alhaji Balewa nkakun, o wa nrau ẹsun apa mọ gbogbo iwa ti Ọgbẹni Smith nhu.

Ọgbẹni Bọla Ige ni "bi enia dudu to sọrẹ to wa ni Ipinlẹ kan ba ti ọgbọn eru ba ioo didi jẹ ti o si nṣe Ijọba, ko yatọ si awọn alawọfu fun tasọrẹ ti o nṣe Ijọba le awọn enia dudu lori.

Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni gbogbo ijọba to wa ni ilẹ Afrika ni o nyọnu si iwa agbara ati ipa ti Ọgbẹni Ian Smith ti o jẹ ọlọtẹ gba fi nṣe Ijọba tani yio mu'mi le awọn alawọdudu lori.

"Awa ẹgbẹ Afẹnifẹre gba gbọ pe iwa ti ẹgbẹ Dẹmọ hu lori ibo ti nwọn di kọja ni Ipinlẹ Iwọ Orun ko yatọ pupọ si iwa ti Ọgbẹni Ian Smith hu ni ilẹ Rhodesia" eyiti awọn enia ti ko pọ ṣejọba le awọn ti o pọ lori.

"Eyiti o y to, gbogbo enia ni o lodi si ibo ti nwọn di ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi eyi ti o ti ba oruko rere ilẹ Naijiria jẹ ni gbogbo agbaiye paapa Ọgbẹni Ian Smith, nitori pe, idi ti on ko fi ni ina didun si iwe ibo ko ṣe, ẹyọ enia kan ni pe iru ibo ti nwọn di ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria je apere, o tun sọ pe, ninu awọn enia ti o dibo ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni ẹlomiran nloyun ibo, bi nwọn si ti di bo tan, ẹniti ẹgbẹ rẹ ko wọle ni nwọn ni ki o wa bẹrẹ Ijọba.

"Gbogbo aiye ti mọ pe, Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ ko le mu'na d'oko bi ẹgbẹ Olomi (NPC) ati Alhaji Balewa ko ba wa lẹhin rẹ, awa ko fẹ ki Alhaji Tafawa Balewa na ja ara rẹ laiya lori ilẹ Rhodesia, o yẹ ki a bere lọwọ Alhaji Balewa pe kini ṣe ti aiya Alhaji Abubakar ko fi ja lori ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

"Ki a sọ otitọ, Ijọba Ọgbẹni Smith ko yatọ si Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ ti Oloye Akintọla nṣe akoso rẹ. Lati ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi ti nwọn ti di ibo itanu ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni awọn enia ti pa iwa nwọn da.



Alhaji Abubakar Tafawa Balewa
Alakoso Ijoba Apapọ Ilẹ Naijiria

## Ọmọ Ogun

"Ẹgbẹ Dẹmọ ṣe ipade ni ọjọ ọjọ'bọ ti ṣe ọjọ kẹsan oṣu yi, awọn Ọlọpa lọ bi ewe rumọ, awọn ọmọ ogun pọ ju enia ti o wa si ipade ni Ibadan.

"Ninu ilu Rhodesia Ọgbẹni Smith si tun sibiti o nu ti o tun ṣe ipade ita gbangba, bi a ba foju inu wo iwa Ọgbẹni Smith pẹlu ti Oloye Akintọla ko si iya to nọ; ootọ ti o wa nibẹ nipe, Ọgbẹni Smith ngbadun ẹmi rẹ ju awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dẹmọ lọ.

"Alhaji Tafawa Balewa ni on yio ri wipe, on pari Ijọba tulasi ti Ọgbẹni Smith nṣe Olori o ti gba ..e, iru rẹ wa nilẹ Naijiria, kini ṣe ti ko kọkọ mu eto la ti di eto ibo si ipinlẹ Iwọ Orun, Ọlọla Balewa n i Rhodesia nbẹ na nọ Afirika, ṣugbọn Alhaji Balewa ti gbagbe pe, ohun ti .lọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun jẹ nkan ti o fẹ pin Naijiria kelekele ko yẹ ki Olori Alakoso Apapọ Ijọba maa ṣe ohun ti o wa nilẹ Rhodesia nigbati Ipinlẹ Iwọ Orun si wa ndaru lọwọ.


NO OJU EWE KẸBA

# NWON PA ENIA MEJO NI ILU SHAGAMU

## Okeaimoye Dukia Segbe Sisun Ina

SHAGAMU:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa ni kutukutu owurọ ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi fi yẹ wa pe enia mẹ ọ ni nwọn a ni ilu Shagamu ninu r gbodiyan kẹtadinlogun oṣu yi lori rogbodiyan to kan to bẹ silẹ ni ilu na ni ọjọ ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi lori rogbodiyan to nṣẹlẹ nipa abẹyẹri ibo si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti awọn enia ipinlẹ na se id bo rẹ ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi.

Ninu rogbodiyan to bẹ silẹ na ni awọn enia kan tun dana sun ile mẹfa ni ilu Shagamu eyiti o jẹ pe gbogbo ile na lo jo pẹlu patapata ti gbogbo awọn dukia ọkẹaimọye si sọ'ege sinu ina.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe ninu awọn ile ti o jona ni ile na ni ile ọmọ ẹgbẹ kan to kuna ninu idibo si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ na to koja ọgbẹni Alfred Oyekọya.

Bakanna ni ile itaja (Shop) nibiti nwọn ti nta awọn ibusun eyiti a npe ni (Vono) ni o jẹ wipe o jona raurau ati awọn oja miran ti nwọn nta ni ṣọbu na eyi ti iye owo rẹ si to £50, 000 lo si tun jona sinu ina to ṣẹlẹ ninu ile ọgbẹni Oyekoya.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa ninu irohin rẹ pe ni kutu owurọ ọjọ ọjọ Bọ ti se ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni awọn enia kan ti nwọn jẹ ọmọ ẹgbẹ oselu ti lọ ko awọn igi uja di oju ọna Shagamu si ọna Eko eyiti o jẹ wipe awọn jandak na si da epo moto si ara igi na ki uwon to dana sun awọn igi ti n on ko si oju ọna na ati ki awọn moto maa le ri ọna na kọja tabi awọn ọlọpa ati soja ti nwọn yio wa lati wa di wọn lọwọ lati si iṣẹ ibi ti nwọn ṣe ṣe na

Irohin na tun fi ye wa pe o to odidi wakati mẹfa ti awọn mọto ti o nọọ lati E o lo si Ibadan Ijẹbu ode tabi ilu miran ati awọn mọto to rẹ lọ si ilu Eko fi duro ti nwọn n ri ọna gba kọja eyiti o jẹ wipe igi ti awọn enia na ko si oju ọna si tun gbina pẹlu

Oniwe Irohin wa ti iṣẹlẹ na se oju rẹ tun se alaye pe asiko ti awọn ti awọn enia na fi ṣẹ iṣẹ ti nwọn ṣe eyiti nwọn fi ko awọn igi nla si oju ọna na ni o ṣe alaye pe ko to iṣẹju mẹwa lọ eyiti ko fun awọn ọlọpa laiye le tete lọ da awọn enia na duro lo ri ohunti nwọn nṣe

Nigbati awọn ọlọpa ati sọja ma fi pe igboro ilu Shagamu ile mẹta lo jẹ wipe o ti jona ranrau eyiti gbogbo awọn dukia to wa ninu awọn ile na si ti jona pẹlu.

Ṣugbọn awọn ọlọpa pẹlu Sọja ti wọn ko lọ si ilu na si tete bẹrẹsi ni se ọna gi nwọn yio ti ṣe le pa ina ti awọn enia na da si oju ọna eyiti awọn enia ko ti ri ọna gba ati pe gbogbo won ero to wa ninu moto ti kori ọna gba koja lọsi ra... ọlọpa ati awọn soja lo... le ri pe awọn te e pa ina nla ti awọn enia na da si oju ọna na eyiti awọn enia ko ti ri ona gba koja.

Nigbati awọn ọlọpa ati soja ... ona gba wo Sagamu ni nwọn ti pe awọn ohunti o ṣo mo inu ti awọn enia dana sun si to £280,00 eyiti o fi le pe gbogbo won nkanna lo lo a rau ran.

Gbogbo awọn ona to gba arin ilu Shagamu lo ni o jẹ wipe awọn enia na si dana si oju ona na ati pe gbogbo awọn enia to nghe ninu ilu Shagamu ati agbegbe rẹ lo si salo patapata nigbati awọn olopa ati soja bẹrẹ si ni ko awọn enia ilu na.

Oniwẹ irohin ni ilu Shagamu tun fi ye wa pe awọn ọlọpa ti mu awọn enia kan loti ohunti o ṣẹlẹ ni ilu na.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe titi di asiko ti a nkọ iwe yi ni rogbodiyan tun nbe silẹ ni awọn agbegbe ilu kan ni ẹkun Ijẹbu Ode eyiti o jẹ wipe ko si dopin rara

Ni ilu Okun-Ọwa ni ẹba Ijẹbu Ode nibiti nwọn ti dana sun Ijoye kan ti o jẹ pataki ni ilu na laaye ni irohin ti tun fi ye wa pe nwọn tun pa enia meji ni ilu na ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtad nlogun oṣu yi.

Irohin na fi ṣe wa pe awọn enia meji ti awọn enia na pa ni ilu OkunỌwa ni a gbọ wipe aṣe ni awọn fi ọbẹ si awọn enia na lọrun bi ẹni pe nwọn npẹran Ileya. Bakanna ni awọn enia n tun dana sun enia kan laaye yẹln epo mọto ni ilu na

Ṣugbọn awọn Ọlọpa ti lọ sibi ti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ at pe awọn Ọlọpa si ti mu awọn enia kan loti ohunti o ṣẹlẹ na

Ninu irohin ti o tun de ọwọ wa ti ọsan ni ẹba Ijẹbu Ode ni a gbọ wipe awọn ọlọpa ti awọn enia meji kan mu lori pe nwọn ka gorod mu ẹpo lo iwe... nwọn ọlọpa ti ko awọn enia na lọ si Ijebu-Ode lati lọ ti wọn mọle


## Ila Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
LORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils da ju pupọ An O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si da pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara pa ayin ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọ ọmọ rẹ yio si sun dada

Ko o ri d ju pe ogun yanmuyanmu o ri erin mẹta yi ... un o

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu elaja kakiri orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS



## WANTED

Advance Apprentice and Apprentice Printers.

Apply In Person

Irohin Imole's Office

16, Bamgbose Street
LAGOS

# NWỌN DA SỌJA KAN DURO LORI ỌRỌ ISELU

IBADAN:- Irohin de ile iṣẹ wa ni ọjọ ojo'Ru tiṣe ojo kẹrindinlogun oṣu yi pe, ọmọ ogun kan ti o wa ni Ibadan ti bẹrẹsi ma kọ awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ni ikọkọ enia le fi t ibọn si Ibiti o jinna to ẹsẹ bata marunlelogoji ni ilu Ibadan eyiti o lodi si ofin iṣẹ ọmọ ogun ti ilẹ Naijiria.

Gẹgẹbi irohin na ti a yọ gbọ pe, Ọga kan ninu ọmọ ogun onipo kẹrin ti o wa ni Ib dan Ọgbẹni Ossai Ugboma ni iwe akọsilẹ kan eyiti o kọ ọro iṣelu ti ko ba ofin mu nipa Ọga agba kan ti orukọ rẹ njẹ Colonel Largema.

Irohin sọ fun wa pe gbara ti nwọn ri aṣ ri Ọgbẹni Ugboma ni nwọn ba ṣe iwa di kekere kan (ki ṣe iwadi lori omọ ogun) eyiti nwọn ni o jẹbi ẹsun na, ni nwọn ba dadu ro.

Ara awọn irohin ti a yọ gbọ ni wipe Ogbẹni na kọ awọn nkan ti o lewu sinu iwe akọsilẹ ti nmu rin awọn ohunti o kọ niyi,

"Pe Ọga agba Colonel sọ ile ti o ngbe di ile awọn Oṣelu eyiti o ko awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ sibẹ paapa Olo ye Akintola pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ.

"Pe o ko awọn ọmọ ẹgbẹ oselu an sinu baraki awọn ọmọ ogun ti o tun ni ki nwọn fi ọwọ si iwe kan eyi ti o tun nkọ wọn bi nwọn yio ti ṣa ki ibọn rifọfa ati bi nwọn yio ti le ma ta sibiti o ba jinna to ẹsẹ bata marunlelogoji.

"Pe o si anfani iṣẹ lo nigba ti o ko awọn ọmọ ogun lọ sibi Isinku ọmọ Oloye Akintola ti orukọ rẹ njẹ Dele Akintola eyiti koni idi kan pataki nwọn ṣe isin ku na ni

"Pe o ba oruko rere omo ogun ilẹ Naijiria jẹ nitori-na awon koni igbẹkẹle ni-nu oga agba Colonel Largemo

Irohin na tun so fun wa pe, iwe akọsilẹ ti Ọgbẹni Ugboma Nmukiri sesi bọ sọwọ ọmọ ogun kan ti orukọ rẹ njẹ Ọgbẹni Jerome Ejeh, ti omọ ogun na jẹ ọmọ Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria, ti omọ ogun ilẹ Hausa na si mu iwe na lọ fun ọga agba patapata

A tun gbọ pe Ọgbẹni Colonel Largema ti o yan asiwaju kan ninu omo ogun ti oruko rẹ njẹ S F Daramọla lati ṣe iwadi iwa Ọgbẹni Ugboma Lẹhin iwadi irohin na tun ṣe afikun pe, awọn sọ Ugboma di ero ẹhin ninu awọn ọmọ ogun

Kete lehin eyi ni ọkan ninu awon omo ogun ti o je ọmọ Hausa Z Malam ba ni ki won kuku da Ọgbeni Ugboma duro lenu Iṣẹ patapata.

A si ti tun gbo pe Ọgbẹni Ugboma ti lọ ba agbejọro kan lati lọ ba pe jọ nile ejọ lori idaduro ti nwon da duro na

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22—Feb 20) Afojudi rẹ po, ṣugbọn bi o ba le ṣe ẹ ki o fiwa afojudi silẹ loni iwo yio ṣe orire gboyi Iwọ yio si tun ni ilosiwaju ninu iṣẹ rẹ

PISCES (Feb 21 Mar 20) Egbogi kan ti o ti lo yio yọnu diẹ ni owuro yi nitoripe yio mu ọ ni otutu nigbati o ba ṣebi ọrọ bari bẹ maṣe ba enikan wiregbe lọ dubulẹ.

ARIES (Mar 21 April 20) Lati oni lọ arọ ara rẹ yio ma tan siwaju, Iwo yio si lọ ajoṣọ ọsan pẹlu awọn to nfẹ ọ iwọ na si nfẹ.

TAURUS (April 21 May 20) Maṣe fi ara silẹ fun aarẹ ti o fẹ yọ ọ lẹnu ki o si ni ogbon inu nitori enikan nibẹ ti yio maṣe lara rẹ si ma funfa si o eyi dara pupo

GEMINI May 21 June 21 Ọpolopo ohunti o jẹ iṣoro fun o ni iwo yio le yanju patapata ti yio ri fun o nitẹ ẹrun iwo yio si gburo oro kan lati odo ajoji enia kan

CANCER (June 22 July 22] Iwọ yio mọ ni ara rẹ wipe a ti gbe ẹru ola kan kuro ni ejika rẹ, tobẹ ti ara rẹ yio ya lati ṣe iṣekiṣe.

LEO (July 23 Aug 22) Ijọgbọn kan si mbẹ nilẹ ti o nfẹ amojuto ni owurọ yi, ṣugbọn ki o maṣe ko ibi ara si nitoripe ti ola ni yio ṣoro, maṣe ti lo gbogbo ogbon ori rẹ silẹ tan.

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ire yio kan o lara ni owuro yi, ṣugbon nigbati osan yio ba fi poo, aarẹ le de si o, ohun ohun ti o ba si lo s, alafia yio de.

LIBRA (Sept 24 Oct. 23) Ire mbẹ o rẹpẹtẹ loni, ti yio si tẹ lorun pe okan rẹ bakanna ni yio ri ni akok yi se jẹjẹ n bi iṣẹ rẹ ki o si jẹki ero ori rẹ pe.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Wahala ati idamu yio de si o lowurọ yi nṣe ni ki o ṣe suru ki o si fi ara balẹ bi o ti wu ki o ri ire mbẹ fun ọ lonakona

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ohun kan ti o nṣe o yio pọ si ni osan itelorun ko le yalaiwa ohun kan ti o ngbero yio ni ilosiwaju

CAPRICORN (Dec 22 — Jan 21] Ṣora fun ohun kohun tise iji ati ajọ ki o si ma fi suru tẹ siwaju ninu ẹ rẹ


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYAMRIN** TỌNIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Tọiki jamonu, tilun ti gbogbo ura Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ di jufun Agbara ati Ajẹbidan iṣẹ lara agbalagba Ọkunrin ati Obinringbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lọsan tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ṣefun daradara ti emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi ubẹ lọ mọ daju pe DYNA MIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di otun pafapata inu rẹ a jọlọ ẹran ara rẹ ti o g hunjọ yio bi yabo dada tiAra rẹ yio gbe kankan ni ugba yio sao pẹla ioq m adeu brode o iyẹn di baṣ



WATERLOO MEDICINE STORES
8 Palm ChurchStreet Phone 22787
LAGOS Nigeria, (Ọja Ita Faji

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

ATI NI ṢỌBU

IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

# Naijiria Yio F'ọwọ Si Iwe Adehun Pẹlu Ijọba Sweden

BKO:—Awọn ilu mẹrin ti finulnnu ti n wọn si jijo jiroro lori ọ a idẹ a ti aw n ra ylo fi m a sowo ọkọ of rufu la ri a araw n ti gbogqo nkan lo fi m a l daad , nwọn bẹ r ipade a n ojo kẹwa titi de ojo kẹti dinlogun oşu yi ev t il Naijiria yan aşoju tisẹ ti awon ilu mẹta toka sl tun yan asoju ti owoo na sibi tpade na.

N'nu ipade na i awọn a oju fun or lẹ ede Naijiria si fi owo si iwe adehun kan lori bi nwon yio ti ma de, oru o ajumoşenọ oko ofurufu tl orilẹ ede Scandinava ti nwon ni awou asoju mẹta fun orilẹ ede to wa lẹ.

Awon asoju ti o ti orilẹ ede Scadinavi ti nwọn na si tun fowosl iwe adehuu kan lori bi nwon y o tişe m a pe oruko ojum şẹ oko ofurufu ti ilẹ Naijiria.

Oruko tl nwon fun oko ofurufu ti orilẹ ede Scan—dinavia eyiti awon ilu nla nla mẹta wa nibẹ ni "Eto ọko ofurufu ti Scandinavia eyiti awọn asoju lati ilẹ Naijiria fi owo sl pẹlu ti awon asoju ilẹ mẹtẹt to ui o ilẹ ede Scand navla na si tun "okọ ofurufu tl Apapọ Ijọba Alailọba Naijiria.

Ipade na wa layọ o si pari tifẹtifẹ; nwọn si fuhun sọkan pe ọna meji ti awọn yio pin et okọ ofurufu na si niyi ti ajọsẹpọ awọn ko si daru.

Ẹ iti o jẹ asiwaju asoju Naijiria ni J fibẹni J. N, Dambọ igbakeji akowe agq nibi işe oko ofurufu awọọ ti o jẹ asoju ilu mẹta na ni ọlọla Marc Giron asoju Ijọba Swedeu ni ilẹ Naijiria ti o tuu jẹ Olori awọn aşoju ilẹ Scandinavia ọlọla Boerge Rasvd asoju Ijọba Danish ni ilẹ Naijiria ati ọlọla Christian Berg Nielsen asoju Ijọba Norway ni ilẹ Naijiria gbogbo nwọn ni o fi ọwọ si iwe adehun na ni orukọ ilu ti awọn ti wa.

Ni ipari idapẹ na gbogbo awku asoju na ni o sọ ni ohun kan pe gbogbo nkan ti awọn şe ni ọjọ na ni o yọri si rere awọn mọ wipe adehun ti awọn şe yi a yio jẹ ki ifẹ ti o so awọn pọ m a gl oro si larin awọn orilẹ ede ti awọn ti wa;


# Kere o Kere o! Akiyesi Pataki

Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanuu Egbogi n LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi şe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nşe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo girikl ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwo ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ilera fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, igbẹ sise, aiko ri igb nşe deede, inudrun ngbọ kugba ara wiwo, Ẹsanri ẹhin didun sisan ati aiko rian kedere ko daro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki ajak ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ şe enia nipa sis di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile mejo abọ (7/-6 pere Igo kekere şile mẹrin abo (4/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Anta ti e ba fẹ ni Şọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba



# GBANJO!

NOVEMBER 15th — DECEMBER 30th 1965



Iwe itumo Ala

jo ibi Omo, Ogun Ajebidan
3s6d di 1s6d

Iwe Afose Isedale Yoruba ati Psalmu Ajebidan.
3s 6d di 2s

Turari 2s 6d Pakẹti di 1/-

o le ri iwe wonyi ra lọdọ :-
SHOYINKA ni 9, Iyalla Street, Mushin.

J. O. SHOYINKA P. O. Box 159 Mushin.